# AWỌN AMUYẸ TI IYAWO KRISTI NI LATI NI

**Matteu 25:1-30; Ifihan 2:1-4; Owe 31:10-31**

**ẸKỌ 363 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitorina ẹ mã ṣọna; nitori ẹnyin kò mọ̀ wakati ti OLUWA nyin yio de" (Matteu 24:42).**

### Gẹgẹ bi Olè Loru

"Ṣugbọn ki ẹnyin ki o mọ̀ eyi pe, bãle ile iba mọ̀ wakati na ti olè yio wá, iba ma ṣọna" (Matteu 24:43). A mọ daju pe ole ki sọtẹ́lẹ nigba ti o ba fẹ jale, ṣugbọn bi eniyan ba mọ̀ pe ẹnikan le wá runlẹ̀ wọ ile oun loru ọjọ kan, yoo pe awọn ọlọpa lati farapamọ si itosi lati mú arufin naa. A kò le ka iru imurasilẹ bẹẹ si iwa ailọgbọn. Niwọn igbati ole si le wá nigbakugba, a o sé ilẹkun wa, a o si wà ni imurasilẹ. O jẹ́ iwa ọlọgbọn lati murasilẹ de ohun ti a mọ pe o n bọwa ṣẹlẹ.

Jesu wi pe nigba ti Oun ba pada wa lati mu Iyawo Rẹ̀ lọ, Oun yoo de gẹgẹ bi ole loru. Gbogbo ọ̀rọ ti Jesu sọ jẹ otitọ wọn yoo si ṣẹ. Nitori naa bi a ba jẹ́ ọlọgbọn a o murasilẹ de akoko ti Jesu yoo pè awọn eniyan Rẹ̀ kuro ninu ayé yii.

O le jẹ ni owurọ nigba ti oorun bẹrẹ si iyọ ni ilu wa, awa ti a si ti murasilẹ lati pade Jesu yoo bẹ̀rẹ̀ ọjọ titun ninu awọn ọrun loke. Ni apa ibomiran ninu ayé akoko yii yoo jẹ́ oru, akoko lati lọ sùn. Awọn eniyan naa tilẹ ti le wi pe "o di owurọ o," lojiji ni a o si ji wọn sinu ogo bibọ̀ Jesu, wọn yoo si wi pe, "ẹ kaarọ o" fun awọn mimọ́ ti wọn yoo ba pade loke. Nibomiran lori ilẹ ayé awọn eniyan yoo gbe ounjẹ ọ̀sán kalẹ lati jẹ , awọn ti eti wọn si ti ṣí si ipè Jesu yoo fi ounjẹ wọn silẹ lati jẹ Ase-Alẹ Igbeyawo pẹlu Jesu ninu awọn Ọ̀run. Lọjọ kan a o gbọ́ awọn ọ̀rọ wọnyii: "Igbeyawo Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan" (Ifihan 19:7). Wo o bi ọjọ naa yoo ti ri! Ṣugbọn a nilati murasilẹ de e.

### Wíwà ni Imurasilẹ

Ki ni itumọ imurasilẹ gan an? Awọn ẹlomiran yoo wi pe: "Jesu gbà mi là kuro ninu ẹ̀ṣẹ. Mo mọ̀ pe a dari gbogbo ẹ̀ṣẹ mi jí mi. Mo ranti igbati Jesu wẹ ọkàn mi ti O si sọ mi di mimọ́. Wo iru ogo ti o kún inu ayé mi nigba ti Jesu fi Ẹmi Mimọ́ wọ̀ mi!" Iyanu ni awọn iriri wọnyii, bi a ba si tẹ̀ siwaju lati maa ka Bibeli ki a si maa gbadura, ki a si maa gbé igbesi-ayé wa gẹgẹ bi Bibeli ti kọ́ wa lẹyin ti a ti ri awọn iriri wọnyii gbà, a o wà ni imurasilẹ nigba ti Jesu ba pè.

Iwọ ha tun fẹran gbogbo eniyan gẹgẹ bi o ti fẹ wọn nigba ti Jesu gbà ọ là? Njẹ o ranti iyipada ọkàn ti o ni si awọn ti o ti korira tẹlẹri nigba ti Jesu wọ inu ọkàn rẹ? Njẹ o ha ranti bi o ti jẹ ifẹ ọkàn rẹ pe ki awọn ẹlomiran ni iru ayọ̀ igbala ti iwọ ni? O gbadura kikan pe ki awọn ẹlomiran le ri igbala, o si sa gbogbo ipa rẹ lati mú ki wọn ni ifẹ si ohun ti ayeraye. Iwọ ha ni itara yii sibẹ?

Jesu gbadura fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, "Sọ wọn di mimọ́ ninu otitọ; otitọ li ọ̀rọ rẹ̀;" lẹyin naa O tun wi pe, "Ki gbogbo nwọn ki o le jẹ ọ̀kan; gẹgẹ bi iwọ, Baba, ti jẹ ọkan ninu mi, ati emi ninu rẹ" (Johannu 17:17, 21). Njẹ o ranti irú alaafia ti o ni nigba ti Jesu sọ ọkàn rẹ di mimọ́? Iwọ kò fẹ jiyàn. Iwọ jẹ igbadun iṣọkan igbagbọ́ ti o wà ninu isọdimimọ́. Njẹ iwọ si tun ni i bi?

Nigba ti a fi Ẹmi Mimọ́ ati ina wọ̀ ọ, Oluwa sunmọ ọ tobẹẹ ti o wu ọ pe ki o rekọja lati ayé yii lọ si Ọrun. O dabi ẹni pe iṣisẹ kan ni. Njẹ ó tún sunmọtosi bẹẹ sibẹ? Jesu wi fun wa pe Olutunu naa, ani Ẹmi Mimọ́, yoo wá lati wá sọ fun wa si i nipa Oun. Yoo sọ fun wa nipa ayọ̀ ti o n duro de wa ni Ọrun. Ẹmi Mimọ́ wá lati sọ fun wa nipa awọn nnkan ti Ibugbe Rẹ̀.

Ṣugbọn bawo ni o ti ni ifẹ́ to lonii lati gbọ nipa ile ti Jesu ti lọ pese silẹ fun ọ? O ha n sọ nipa rẹ̀ to bi o ti n sọ nipa ile ti o n gbé inu rẹ̀ nihin?

A ha n gbé igbesi-ayé wa lojoojumọ pẹlu èrò naa ninu ọkàn wa pe Iyawo Kristi ni awa iṣe, ati pe a nilati ṣe ara wa yẹ bẹẹ? A ha n ṣọra pe ki o maṣe si ohunkohun ninu ayé wa ti ki yoo tẹ́ Jesu lọrun bi O ba pè wa lonii si Igbeyawo naa? Eniyan le gbé igbesi-ayé ti o dara, ki o ni itara tootọ lati mú ki awọn ẹlomiran maa gbé igbesi-ayé wọn gẹgẹ bi Ofin Wura nì ti wi, sibẹ ki o má ni ifẹ Jesu lọkàn rẹ̀ gẹgẹ bi o ti ni i nigba ti o ri igbala.

### Sisọ Ifẹ Iṣaaju Nù

Nigba ti Johannu Apọsteli wà lori Erekuṣu Patmo, a fi iran hàn an nipa irú ipo ti awọn ijọ ti o wa ni Asia wà. Ohun ti Jesu sọ fun un nipa ijọ Efesu ni yii: "Emi mọ̀ iṣẹ rẹ, ati lãlã rẹ, ati ìfarada rẹ, ati bi ara rẹ̀ kò ti gba awọn ẹni buburu: ati bi iwọ si ti dan awọn ti npè ara wọn ni apọsteli, ti nwọn ki si iṣe bẽ wo,

ti iwọ si ri pe eleke ni wọn; Ti iwọ si farada ìya, ati nitori orukọ mi ti o si fi aiya rán, ti ãrẹ̀ kò si mu ọ. Ṣugbọn eyi ni mo ri wi si ọ, pe, iwọ ti fi ifẹ rẹ iṣaju silẹ. Nitorina ranti ibiti iwọ gbé ti ṣubu, ki o si ronupiwada, ki o si ṣe iṣẹ iṣaju" (Ifihan 2:2-5).

A ti gba awọn eniyan wọnyii là nitootọ. Jesu wi pe, "Ranti … ibiti iwọ gbé ti ṣubu." Wọn ti ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wọn lẹẹkan ri, ṣugbọn wọn ti fasẹyin. Wọn ti ṣiṣẹ pupọ fun Jesu, wọn si n ṣe e sibẹ. Wọn ti ni suuru, eyi ti o ju ti ọ̀pọlọpọ eniyan ti wọn n pe ara wọn ni Onigbagbọ́. Wọn tilẹ fi itara gbigbona dá iwa buburu awọn ẹlomiran lẹbi. Wọn rò pé ohun ti awọn n ṣe nì awọn n ṣe wọn fun Jesu. Ṣugbọn wọn ti sọ ifẹ iṣaaju nì nù wọn kò si yẹ lati jẹ́ Iyawo Kristi.

Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa pe bi a ba ni igbagbọ́ ti o le ṣi awọn oke nidi, sibẹ bi a ko bá ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wa, a kò jẹ́ nnkankan. A le jọwọ ara wa lati fi ṣe ẹbọ, a le fi gbogbo owó ti a ni ran awọn talaka lọwọ, ṣugbọn eyi ni ki yoo sọ wa di Iyawo Kristi. A nilati ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wa ki a si pa a mọ́ sibẹ. "Jù gbogbo rẹ̀ lọ, ẹ ni ifẹ ti o gbóna lãrin ara nyin: nitori ifẹ ni mbò ọ̀pọlọpọ ẹ̀ṣẹ mọlẹ" (1 Peteru 4:8).

**Awọn Wundia Alaigbọ́n**

Ninu owe awọn wundia marun-un ti o ṣe ọlọgbọn ati marun-un alaigbọ́n a sọ fun wa nipa awọn ẹgbẹ ẹlẹsin kan, ti olukuluku wọn n reti bibọ̀ Oluwa. Gbogbo wọn ni o rò pé awọn ti murasilẹ, ṣugbọn marun-un ninu wọn dabi awọn ti o wà ni ijọ Efesu. Wọn ti sọ "ifẹ wọn iṣaju" nù. Awọn naa pẹlu n huwà gẹgẹ bi awọn marun-un iyoku ti n huwà. Wọn n ṣe iṣẹ kan naa, ṣugbọn ọkàn wọn kò ri bakan naa. Nigba kan ri wọn ti ni ifẹ Ọlọrun, ṣugbọn wọn ti jẹ ki o jò sọnu titi atupa wọn fi ṣofo. Ki i ṣe gbogbo awọn ti o bẹ̀rẹ gẹgẹ bi Onigbagbọ́ ni yoo wà ni imurasilẹ nigba ti Jesu ba de. "Ẹniti o ba foriti i titi fi de opin, on na ni a o gbala" (Matteu 10:22).

**Iyawo Kristi**

Bawo ni a ṣe le gbé igbesi-ayé wa ti ororo naa ki yoo fi jò danu, ki atupa wa si ṣofo? Ninu Owe 31 a ṣe apejuwe obinrin rere kan, ẹni ti o dabi Iyawo Kristi fun wa.

"Aiya ọkọ rẹ̀ gbẹkẹle e laibẹ̀ru" (Owe 31:11). Jesu ni ọkọ naa. Njẹ Oun le gbẹkẹle ọ laibẹru? Oun ti lọ nisisiyii. Njẹ o yẹ ki Oun maa ṣiyemeji nitori ihuwàsi rẹ lẹyin ti O ti lọ? Gbogbo iṣẹ wa nilati jẹ́ pẹlu ero yii ninu ọkàn wa: Njẹ Jesu yoo fẹ ki emi ṣe eyi bi? Bi ẹnikan ninu aye ba n ṣakiyesi iwa mi, yoo ha ri pe Iyawo Kristi ni emi iṣe? Mo ha jẹ́ ọkan pẹlu Rẹ̀ ninu iwa ati igbesi-ayé mi niwaju awọn eniyan gẹgẹ bi ọkọ ati aya? "Rere li obirin na yio ma ṣe fun u, ki iṣe buburu li ọjọ aiye rẹ̀ gbogbo".

**Iṣoore**

"O fi ọgbọ́n yà ẹnu rẹ̀: ati li ahọn rẹ̀ li ofin iṣeun" (Ẹsẹ 26). Wo ọ̀pọlọpọ igba ti awọn eniyan n gbagbé lati ṣoore! "Ifẹ a mã mu suru, a si mã ṣeun" (1 Kọrinti 13:4). Oun a maa ṣoore ki iṣe fun kiki awọn ọrẹ rẹ̀ ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ̀ ti o sunmọọ, ki isi iṣe ni igba kọọkan. Iṣoore jẹ́ ofin fun un. Oun a maa ṣore lai ronu nipa rẹ̀. Gbogbo eniyan ni o kà yẹ lati ṣoore fún, ati awọn ti kò tilẹ fẹran rẹ̀ pẹlu. O le gbadura fun awọn ti n fi arankan ba a lò. "Ifẹ ki iṣe ilara; ifẹ ki isọrọ igberaga, ki ifẹ̀." "Eso ti Ẹmi ni ifẹ, ayọ̀, alafia, ipamọra, iwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́, iwa tutù, ati ikora-ẹni-nijanu" (Galatia 5:22, 23). Ifẹ Ọlọrun si ni fun wa lati so iru eso bawọnyi lọpọlọpọ. Iru eso wọnyii a maa ti inu kiki ọkàn ti o kún fun ifẹ Ọlọrun jade wa.

**Ririn yẹ**

Paulu Apọsteli sọ fun wa: "Ki ẹnyin ki o mã rin bi o ti yẹ fun ipe na ti a fi pè nyin, pẹlu irẹlẹ gbogbo ati inu tutù, pẹlu ipamọra, ẹ mã fi ifẹ farada a fun ẹnikeji nyin; ki ẹ si mã lakaka lati pa iṣọkan Ẹmi mọ́ ni idipọ alafia" (Efesu 4:1-3).

Bi a ba wi pe Onigbagbọ́ ni awa iṣe a nilati fi hàn nipa igbesi-ayé wa. Ero ti o ga julọ ninu ọkàn ọmọ Ọlọrun ni lati wà ni imurasilẹ nigba ti Jesu ba de. Oun a maa gbiyanju lati tẹ̀ siwaju lojoojumọ ki oun ba le ni gbogbo ọsọ ẹmi ti o yẹ. Oun a maa ka ẹsẹ bi iru eyi: "Ẹ má si ṣe mu Ẹmi Mimọ́ Ọlọrun binu, ẹniti a fi ṣe èdidi nyin dè ọjọ idande. Gbogbo iwa kikorò, ati ibinu, ati irunu, ati ariwo, ati ọ̀rọ buburu, ni ki a mu kuro lọdọ nyin" (Efesu 4:30, 31). Oun a maa bẹ Ọlọrun lati ran an lọwọ lati mú ayé rẹ̀ bá Ọrọ naa mu. Oun ki ima wò tabi ki o maa sọ̀rọ̀ nipa abuku ti o wà ni igbesi-ayé ẹlomiran.

**"Maṣe maa wá abuku kiri bi o ti n lọ ni ayé,**

**Nigba ti o ba tilẹ ri wọn**

**O dara, o si jẹ ohun rere lati mú oju rẹ kuro ninu wọn**

**Ki o si maa wá ire ti o wà lẹyin wọn."**

“Nitorina, bi ayanfẹ Ọlọrun, ẹni mimọ́ ati olufẹ, ẹ gbé ọkàn iyọ́nu wọ̀, iṣeun, irẹlẹ, inu tutù, ipamọra” (Kolosse 3:12). Iru wọnyii ni iwa Iyawo Kristi.

**Iṣẹ́ Iyawo Naa**

“Ati Ẹmi ati iyawo wipe, Mã bọ̀” (Ifihan 22:17). Iṣẹ Iyawo Kristi ni eyi. Oun a maa bá Ẹmi ṣiṣẹ lati pe awọn ẹlẹ̀ṣẹ̀ wá si ironupiwada. Oun a maa mú “onjẹ rẹ̀ lati ọ̀na jijin rére wá” (Owe 31:14), a si maa fi awọn ohun ti Ọrun bọ́ ọkàn rẹ̀. Oun kò tun ni ifẹ́ si ohun ti ayé yii ju bi o ti yẹ lati gba ọkan rẹ̀ kan titi Jesu, Ọkọ Iyawo ọkàn rẹ̀, yoo fi dé.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni a mọ̀ nipa akoko ti Jesu yoo de?

2 Ki ni ṣẹlẹ si wa nigba ti a ba da wa lare?

3 Ki ni isọdimimọ́ n ṣe fun wa?

4 Ki ni Jesu wi pe Ẹmi Mimọ yoo sọ fun wa?

5 Njẹ nisisiyii igbagbọ́, ireti, ati ifẹ n bẹ, ewo ni o tobi ju?

6 Ki ni Jesu wi pe o kuna ninu ijọ Efesu?

7 Ki ni ọkunrin ọlọgbọn nì sọ nipa iṣoore obinrin oni iwa-rere nì?

8 Ki ni eso ẹmi?

9 Ki ni iṣẹ́ Iyawo Kristi?